# ORÍ ÒKÈ INÁ ÀTI IṢẸ́ ÌYANU

Olú Ilé Iṣẹ́ Ìránṣẹ́, Ìpínlẹ̀ Èkó, Nigeria.

**Oṣù Kẹrìn, Ọdún 2024**

**Agbára Gbọ́dọ̀ Pàrọ̀ Ọwọ́**

**OṢÙ KẸRÌN, ỌDÚN 2024 – ITUSILẸ TO JINLẸ (1)**

1. **Agbára mbẹ nínú ẹ̀jẹ̀ Jésù,**

‘Torí ó w’ẹ̀ṣẹ̀ mi nù,
Mo sì mọ̀ pé ìhìn Rẹ̀ lí ayọ̀,
Ó sòkùn mi di’mọ́lẹ̀.

Ègbè
Agbàra mbẹ, Agbára t’ó n ṣiṣẹ́ ìyanu
Agbára mbẹ, Agbára tí ó nwẹ̀ wá mọ́,
Mbẹ nínú ẹ̀jẹ̀ Jésù.

2. Agbára mbẹ nínú ẹ̀jẹ̀ Jésù,

Ó gbà mí lọ́wọ́ ẹ̀bi,
‘Gbàtí mo k’ẹ́rù ẹ̀ṣẹ̀ mi tọ̀ Ọ́ wá,
Ẹ̀jẹ̀ Rẹ sì wẹ̀ mí mọ́.

3. Èmi mọ ire t’ẹ́jẹ̀ ná nṣe,

Ó ti sọ wá di titun,
Nípa ẹ̀jẹ̀ Rẹ iyebíye nà,
Mo di mímọ́ tìtí láí.

1. **Nípa ìfẹ́ Olùgbàlà**

Kì y’ó sí nkan
Ojú rere Rẹ kì padà
Kì y’ó sí nkan;
Ọ̀wọ́n lẹ̀jẹ̀ t’ó wò wá sàn;

Pípé l'èdìdì ór'ọ̀fẹ́;
Agbára l'ọwọ́ t'ó gba ni
Kò lè sí nkan

2. Bí à wá nínú ìpọ́njú,
Kì y'ó sí nkan;
Ìgbàlà kíkún ni tiwa,
Kì y'ó sí nkan
Ìgbẹ́kẹ̀lé Ọlọ́run dùn;
Gbígbé inú Krístì l'érè
Ẹ̀mí sì nsọ wá di mímọ́,
Kò lè sí nkan

3. Ọjọ́ ọ̀la yó sì dára
Kì y'ó sí nkan
'Gbàgbọ́ lè kọrin n'nú 'pọnjú
Kì y'ó sí nkan
A gbẹ́kẹ̀lé 'fẹ́ Bàbá wa;
Jésù nfún wá l'óhun gbogbo
Ní yíyè tàbí ní kíkú;
Kò lè sí nkan.

## ỌRỌ̀ AGBÁRA

1. Bàbá mi, jẹ́ kí ọwọ́ àánú Rẹ ṣàwárí mi fún ìfọwọ́kàn ìtayọ lónìí, ní orúkọ Jésù.
2. Gbogbo agbára tí wọ́n yàn láti gé ògo ìràwọ̀ mi kúrú, àkokò rẹ dópin lónìí, kú, ní orúkọ Jésù.

3. Ọlọ́run, jẹ́ kí àánú Rẹ ṣàwárí mi lónìí fún àwọn ilẹ̀kùn tó ṣí í, ní orúkọ Jésù.
4. Àwọn agbára tí wọ́n yàn láti fi gbogbo ìgbìyànjú rere mi láti ṣe àṣeyọrí ṣòfò, gba ìparun nípa agbára Ọlọ́run, ní orúkọ Jésù.
5. Nípa àánú Ọlọ́run, gbogbo agbára tí wọ́n yàn láti mú ìjákulẹ̀ bá ayànmọ́ mi yóò kú lónìí, ní orúkọ Jésù.
6. Gbogbo agbára tí wọ́n yàn láti fa àwọn ohun rere mu kúrò nínú ayé mi yóò ṣubú lulẹ̀ kú lónìí, ní orúkọ Jésù.
7. Bàbá mi, Ìwọ ni Jèhófà Jirè, bẹ ètò-ìṣúná mi wò pẹ̀lú ọwọ́ ìpèsè Rẹ, ní orúkọ Jésù.

## ÀDÚRÀ ÀDÁGBÀ

**ÌJẸ́WỌ́ - ORIN DÁFÍDÌ 91**

1. Ọlọ́run, dìde, kí O sì fàtu ohunkóhun tí O kò gbìn sínú Orí Òkè Iná àti Iṣẹ́ Ìyanu, ní orúkọ Jésù.
2. Ọlọ́run, jẹ́ kí iná ìsọjí bà lé Orí Òkè Iná àti Iṣẹ́ Ìyanu, ní orúkọ Jésù.
3. Agbára tí wọ́n gbìn sí ìgbà èwe mi láti yọ ìlera mi lẹ́nu, mo wó ẹnubodè rẹ lulẹ, ní orúkọ Jésù.
4. Gbogbo omi ìkorò àìsàn tó n ṣàn nínú ìdílé mi láti ọ̀dọ̀ àwọn agbára búburú ilé bàbá mi, gbẹ dànù, ní orúkọ Jésù.
5. Okùn ìyówù tó de ìran ìdílé mi mọ́ agbárakágbára ibi ilé bàbá mi, já, ní orúkọ Jésù.
6. Gbogbo ẹ̀mí aláálẹ̀ tó n yọ ìlera mi lẹ́nu, gba ìyarọ, ní orúkọ Jésù.
7. Níbo ní Ọlọ́run Èlíjàh wà? Dìde, dójúti gbogbo àjogúnbá ibi agbára ilé bàbá mi, ní orúkọ Jésù.

## ÀDÓ Ọ̀RỌ̀ NÁÀ

**Máttéù 11:28-30:** Ẹ wá sọ́dọ̀ mi gbogbo ẹ̀nyin tí nṣiṣẹ́, tí a sì dì ẹrù wúwo lé lórí, èmi ó sì fi ìsimi fún nyín. Ẹ gba àjàgà mi sí ọ̀run nyín, kí ẹ sì

ma kọ ẹ̀kọ́ lọ́dọ̀ mi; nítorí onínú tútù àti onírẹ̀lẹ̀ ọkàn lí èmi; ẹ̀nyin ó sì rí ìsimi fún ọkàn nyín. Nítorí àjàgà mi rọrùn, ẹrù mí sì fúyẹ́.

**Máttéù 10:1:** Nígbàtí ó sì pe àwọn ọmọ-ẹ̀yìn rẹ̀ méjèjìlá sí ọ̀dọ̀, ó fi agbára fún wọn lórí àwọn ẹ̀mí àìmọ́, láti ma lé wọn jáde àti láti ṣe ìwòsàn gbogbo àrùn àti gbogbo àìsàn.

**Máttéù 9:35** Jésù sì rìn sí gbogbo ìlú-nlá àti ìletò, ó nkọ́ni nínú sínágọ́gù wọn, ó sì nwàsú ihìnrere ìjọba, ó sì nṣe ìwòsàn àrùn àti gbogbo àìsàn lí ara àwọn ènìyàn.

**Máttéù 14:14** Jésù jáde lọ, Ó rí ọ̀pọ̀lọpọ̀ ènìyàn, inú Rẹ sì yọ sí wọn, Ó sì ṣe dídá àrùn ara wọn.

**Máttéù 9:21** Nítorí ó wí nínú ara rẹ̀ pé, Bí mo bá sà lè fi ọwọ́ kan aṣọ rẹ, ara mi ó dà.

**Márkù 5:34** Ó sì wí fún u pé, Ọmọbìnrin, igbàgbọ́ rẹ mú ọ láradá; ma lọ lí àláfíà, kí ìwọ kí ó sì sàn nínú àrùn rẹ.

**Lúkù 4:18** Ẹ̀mí Olúwa mbẹ lára mi, nítorítí ó fi àmì òróró yàn mí láti wàsú ihìnrere fún àwọn otòsì; ó ti rán mí wá láti ṣe iwòsàn àwọn ọkàn oníròbínújẹ́, láti wàsú ìdásílẹ̀ fún àwọn ìgbèkùn, ìtúnríran fún àwọn afọ́jú àti láti jọ̀wọ́ àwọn tí a pa lára lọ́wọ́.